


# EYI NI OJO AWON OJA ILE WA.

### OJO AJE 3RD DECEMBER (MONDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Mushin. |
| Abeokuta | Owode, Otta, Abalabi, Sodeke, Omida, Ilawo, Owowo, Obafemi, Oja-Oje |
| Ibadan | Ikenne, Ago-Owu, Eruwon, |
| Ijebu | Omu, Ago-Iwoye |
| Ijesha | Ijebu-Ijesha, Oshu, Itagu, Odo gbo, Iloko, Ipetu, Owode, Idoko, Idoka, Ilare. |
| Ondo ati Eti Odo | Agbabu, Igbogi, Ishua, Erinketa |
| Egbado | Ilorunda, Kajola, Ilobi, Erede |
| Ogbomosho | Araromi, Iresha |
| Ekiti | Erekesan |
| Ibinni | Osele |
| Delta | —— |
| Igbajo | Iloro |

### OJO ISEGUN 4TH DECEMBER (TUESDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Agege, Iketa, Ebute-Ero, Ojo, Ajido |
| Abeokuta | Lafenwa, Obada, Oba, Kajola, Ajegunle, Idomo, Orunmaki, Itori |
| Ibadan | Ibuko, Lalupon |
| Ijebu | Ibefun, Atikori, Imushin, Ijesha-Ijebu, Isara, Imodi, Ipara, Mamu, Mojoda. |
| Ijesha | Esa-Oke, Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Esa-Odo, Ijeda, Ikeji, Eti Oni. |
| Ondo ati Eti Odo | Igbo-Egunren, Atijere, Oni, Ebiwo. |
| Egbado | Idi-Emi, Ibeshe, Lasilo, Atta |
| Ogbomosho | Oko |
| Ekiti | Ifaki, Okemesi |
| Ibinni | Iromi |
| Delta | —— |
| Igbajo | |

### OJO 'RU 5TH DECEMBER (WEDNESDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Oyingbo. |
| Abeokuta | Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasinmi |
| Ibadan | Olode, Ogunjana, Lagun |
| Ijebu | Aiyepe, Sagamu, Ita-oru, Ogere, Irolu, Ita-Iloti, Itele, Oyingbo, Ijebu-Ijesha, Ibodi, Ibode, Kajo-la, Oluwa'da. |
| Ijesha | |
| Ondo ati Eti Odo | Abigi, Aiyetoro, Oka, Ilara, Epe |
| Egbado | Alagba, Ilaro, Sunwa, Iboro |
| Ogbomosho | Obada, Gambari |
| Ekiti | Ilogbo, Oke-Aiyedun, Idogun |
| Ibinni | Eko |
| Delta | —— |
| Igbajo | |

### OJO 'BO 6TH DECEMBER (THURSDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Obun-Eko |
| Abeokuta | Atan, Agbado, Ifo, Itoku, Isabo, Odeda, Ibara. |
| Ibadan | Ijaiye-Orile, Iresi, Obada, Egbe-da, Oyedeji |
| Ijebu | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imope, Isban, Isara, Imodi, Akesan |
| Ijesha | Ilase, Epe, Iloba, Iperindo, Imu-roko, Erinmo, Esa-Oke. |
| Ondo ati Eti Odo | Agirifon-Ilutitun, Odojomo, Igbotako, Ileoluji, Obunkekere, Aiyetoro, Tutu, Ilandu, Ado-Odo |
| Egbado | |
| Ogbomosho | Iresa-Du, Arolu, Egbeda, Iaba-ta, Oke Ireale |
| Ekiti | Egosi, Odo-Aiyedun |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajo | Kokori |

### OJO ETI 7TH DECEMBER (FRIDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Mushin, Badagry |
| Abeokuta | Otta, Abalabi, Sodeke, Owode, Omida, Ilawo, Owowo, Obafemi, Oja-Oje |
| Ibadan | Ikenne, Okunowo, Erunwon |
| Ijebu | Omu, Ago-Iwoye |
| Ijesha | Ijebu-Ijesha, Osu, Itagu, Odoko, Iloko, Odogbo, Owode, Idoka, Ilare, Ita Apa. |
| Ondo ati Eti Odo | Ishua, Aye, Erinketa, Agbabu, Igbogi |
| Egbado | Ilobi, Igbogila, Ijoun, Imasai |
| Ogbomosho | Araromi, Iregbo |
| Ekiti | Erekesan |
| Ibinni | —— |
| Delta | —— |
| Igbajo | Iloro |

### OJO ABAMETA 8TH DECEMBER (SATURDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Agege, Ikeja |
| Abeokuta | Lafenwa, Obada, Oba, Kajola, Ajegunle, Idomo, Orunmaki, Itori |
| Ibadan | Lalupon, Ibuko |
| Ijebu | Isara, Imodi, Ibefun, Atikori, Imushin, Ijesha-Ijebu, Mamu |
| Ijesha | Ijesha-Ijebu, Ipara, Mojoda, Esa Oke, Iwara, Ejioro, Odo, Ibo-kun, Esa-Odo. |
| Ondo ati Eti Odo | Igbo-Egunren |
| Egbado | Idi-Emi, Lasilo, Ibeshe, Atta |
| Ogbomosho | Oko |
| Ekiti | Ifaki, Okemesi |
| Ibinni | Uromi |
| Delta | —— |
| Igbajo | —— |

### OJO AIKU 9TH DECEMBER (SUNDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Oyingbo, Ejinrin. |
| Abeokuta | Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasinmi. |
| Ibadan | Ogunjana, Lagun, Ilogbo, Olode |
| Ijebu | Aiyepe, Sagamu, Ilasan, Ogere, Irolu, Itele, Ita-Iloti |
| Ijesha | Ijebu-Ijesha, Ibodi, Ibode, Kajo-la, Oluwa'da. |
| Ondo ati Eti Odo | Oka, Ilara, Abigi, Aiyetoro, Epe |
| Egbado | Alagba, Ilaro, Sunwa, Iboro, Jiggu |
| Ogbomosho | Obada, Gambari |
| Ekiti | Ilogbo, Oke-Aiyedun, Idogun |
| Ibinni | Eko |
| Delta | —— |
| Igbajo | —— |

### OJO AJE 10TH DECEMBER (MONDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Obun Eko |
| Abeokuta | Atan, Agbado, Ifo, Itoku, Isabo, Odeda, Ibara, Itori, Oja-Ifo |
| Ibadan | Ijaiye-Orile, Iresi, Obada, Egbe-da, Oyedeji. |
| Ijebu | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imope, Isban, Isara, Imodi, Ajegunle |
| Ijesha | Esa-Oke, Ilase, Epe, Iloba, Ipe-rindo, Imuroko, Erinmo. |
| Ondo ati Eti Odo | Odojomo, Igbotako, Ileoluji, Obunkekere, Agirifon-Ilutitun, Aiyetoro, Tata, Ilandu, Ado-Odo |
| Egbado | Iresa-Du, Arolu, Egbeda |
| Ogbomosho | Egosi, Odo-Aiyedun. |
| Ekiti | |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajo | Kokori |

## ITUMO ALO

1. Owu.
2. Oju.
3. Omi-oju.
4. Ina.
5. Aja (ceiling).
6. Igunnu ara ile.
7. Oja.
8. Ojo (rain).
9. Oju, imu ati enu.
10. Ile, orun ati awon ara.
11. Omu-obinrin.
12. Ilekun.
13. Ire.
14. Ope (palm tree).
15. Odo (river).

## Ẹ ma a ka Iwe IROHIN YORUBA nigbagbogbo fun irohin aladun






## Iwora Lakuregbe

NIPTIN NI IDERA GAN AN WA

Fun oko kere lowo laku-regbe o je ohun pataki lati ... De Witt's Pills ... De Witt's Pills je egbogi ... lakuregbe ...




IJERI SI WA

Egbogi De Witt's Pills je ... gbogbo awon ... ni je pipe.

DE WITT'S PILLS

for Kidney and Bladder Trouble




# Ęgbę Afęnifęre pegede!

OGO ni fun Olorun fun irohin ayo ti a gbo nipa ominira wa. Sa'-kata re, Asiwaju wa rere, Ologa Oloye Obafemi Awolowo. Muso fun Egbe Afenifere. Barika, enyin enia Ipinle Iwo-Orun. A rubo, ebo da; ajankoro-dugbe.!

Nigbati mo gbo irohin oro Olu-Akowe Ijoba Gesi fun ilu okere, Ogbeni Alan Lennox-Boyd, okan mi korin bi awon omo Israeli pe "Oluwa se ohun nla fun wa". Beni; ti Ipinle Iwo Orun to ope. Sugbon a ko gbodo gbagbe awon ti o fi emi otito, Isera-emi, ifaramora ati Iakaye se ise ilu wa lona ti o ye fun iwin gbogbo agbaiye, ti o si fi han Ijoba Gesi pe Ipinle Iwo-Orun ki ise kekere ninu ile awon omoluwabi enia.

Ni ti awa ore ati alatilehin Egbe Afenifere, awa le so pe "ohun tita bo sodo wa ni ile rere, awa ni ogun rere". Nitoto, Oluwa ti gbo ohun ebe wa. Ni ti Oloye Obafemi Awolowo ati awon omo-ogun re, iran yi ati iran ti mbo yio ma ranti won bi olododo titi aiye nitori, bi awon ba ti gba ese laiya won ti awon ba si ti fi imotara-enikan, aisoto ati ainani fun ire ati ilosiwaju awon enia ati ilu won se Ijoba Ipinle-IwoOrun, Oluwa ki ba ti gbo ohun wa bi o ti ri fun wa loni.

Ija ominira Naijiria ti bere lati odun pipe, sugbon ko da mi loju pe egbe oselu kan tabi agbajo awon oselu kan ja ija na pelu emi otito bi ti Egbe Afenifere (Action Group) labe Ogagun Lisa Ijeun. Bi oro didun, igberaga, ihale ati iwa rudurudu ba le gbe orile-ede leke, Egbe Alakuko iba ti jagunmolu fun ominira Naijiria, nitoripe akitiyan won po, be si li ti awon alatilehin won, lati gba ona eburu, ona etan ati hadahada yo si ominira.

Awa ti fi oju wa ri, awon oselu ti Egbe Afenifere si ti fi han wa, ohun wonyi to ye gbogbo fun igbala orilede. Ifokanbale wa labe Ijoba won; aboyun nri itoju; alaisan nri iwosan agbe nroko bodunde; onisowo nri iranwo gba. Kakiri Ipinle Iwo-Orun, ojo idera nro, orun ododo nla sokan tomode-tagba nitori ti eko ntankale, ife-si-alafia ilu si nga soke.

Nkan wonyi ngele nitoriti awon oselu Ipinle Iwo-Orun ko fi etan se ise won. Eyi si mu ki awon enia ni igbekele ninu Ijoba. Bi o tile je pe awon Egbe Alakuko (NCNC) ko saigbiyanju lorisirisi ona lati fi ota sarin Ijoba ati awon enia Ipinle Iwo-Orun, sibesibe, otito bori; ise awon Egbe Afenifere fi han awon enia pe igbala Ipinle Iwo-Orun ati ti gbogbo ilu Naijiria yio ti owo Egbe Afenifere jade.

Oloye Obafemi Awolowo so pe Egbe Afenifere fe ominira fun gbogbo ilu Naijiria. Otito li eyi. Ise Egbe Afenifere ti fi aniyan rere won han. Sugbon o se enia awon olufe ominria Naijiria-lanu lati ri bi Egbe Alakuko (NCNC) ti npafo ninu awon nkan ti nro orile-ede wa. Nipa iwa ati ise won, won nfi han wa pe enu lasan li awon fi fe ominira, okan won si fe wa loko eru. Laije pe awon ronupiwada, ki nwon feran otito ati iwa ododo bi ti Egbe Afenifere, ominira fun gbogbo ilu Naijiria yio gba akoko.

E mase jeka tan ara wa je. Egbe Alakuko li ota ominira Naijiria. E jeka so fun Egbe Alakuko pe ki nwon huwa to le mu ominira wa. Iwa aganmigan, ojole, anikanjopon ati robi-rebi ki ise iwa to le fun orile-ede ni ominira.

Otito so Ipinle Iwo-Orun dominira, awa si nyo. Sugbon, enyin ara, nisisiyi gan ni a gbodo tubo ni emi isera-emi, emi irepo ninu nkan ti jemo alafia ati ilosiwaju wa ati emi ajumose ise po fun ire. Awa ti mo bi agbara Egbe Afenifere ti po to; Egbe na ti ja ija rere fun wa. Ko si ohun ti a le fi san ore ju pe ki gbogbo wa pinnu, ki a si fi tokantokan seleri, lati ti Egbe na lehin ninu ise rere re. E mase gbagbe, alafia lo ti alafia eiye. Ki Olorun fi ise rere Egbe Afenifere yin ilu Naijiria! Egbe Afenifere pegede!

ALAKORI

## Enia mewa fi ar pa ı ile Sinima

ENUGU.

ENIA mewa li ekunrin ati Tobinrin ni e fi ara pa pupe ju ni ibi iworan sinima (Rio Cinema Theatre) ti Enugu ni ojo Aje ti ise ojo kejila osu yi nigbati enikan lara awon oluworan ojo na kigbe idagiri ina o! ina o!! ina o!!! lai je pe ina na sele nitoto.

Ni ibiti gbogbo won ti nsa asala fun emi won, awon miran fo ferese ti o yi ile iworan na ka, be e ferese ga ju ese mewa lo. opolopo ni o si gabu-korobata sile ni enu ona abajade ti opolopo si ngun ori won kola. Nwon ko si mo eniti o kigbe ijaiya ina nla na doni-oloni.


# Irohin rere

# Nisisiyi! KORA TEA wa nihin lati din o ni'nawo ku




## O DINWO JU AWON TEA MIRAN LO

O dehin dandan! Tea titun ti Brooke Bond pile se daradara fun West Africa. Tea ti o din o ni na'wo ku nitoripe o dinwo ku fun o ju awon tea miran lo. Tea ti o dara nigbagbogbo nitoripe Brooke Bond li o se e ati pe nigbagbogbo li o nwa ni akotun nitori akanse edidi ti nwon fi di i ni ilgnm aromiyo ti ki i je ki o rin. "KORA" tea aladun

Brooke Bond ni egbegberun eeka-ile ogba tea ju awon egbe onisowo tea miran lo l'aiye. Nwon ni awon onibara tiwon ninu gbogbo oja nla tea agbaiye. Nisisiyi, pataki ni fun West Africa, nwon ti se "KORA" tea—o dinwo, o l'adun, o l'akotun. Ra "KORA" tea loni.

**Oşeşe ni o wa nigbagbogbo. O dara nigbagbogbo. Opolopo ife ni o wa ninu paketi kan.**

*Nwon pile se e ni pataki fun West Africa lati owo aniyi k'aiye*

# Brooke Bond

RA DIE LONI!




# Awọn Aganin gba Ẹgbẹ Amuludagba Iwọ-Orun Naijiria lalejo ni Accra











## Hadji Ọlọrunṣogo jẹ Imam

## BALẸ IDOWU KU

## Ọmọ titun alẹjo Aiye





